## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì lónìí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krísti gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kí ló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023





## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì lónìí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krísti gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àìnípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kí ló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023




Gbogbo ẹ̀dá lóní ìtẹ̀sí tí ó kún fún ẹ̀ṣẹ̀, tí a sì wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run nítorí àìgbọràn Ádámù àti Éfà (Róòmù 5:12). Ọlọ́run máa ń bínú sí ẹ̀ṣẹ̀, yóò sì ṣẹ̀dájọ́ ẹ̀ṣẹ̀. Nítorí èyí, Ó rán Ọmọ Rẹ̀ kanṣoṣo, Jésù Krístì sí wa gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti yè bọ́ ìdájọ́ ìkẹyìn Rẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀, tí yóò wá pẹ̀lú ìbínú àti òdodo (Jòhánù 3:16). Jésù Krístì san gbèse ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá lórí Àgbélébùú ti Kálfárì, kí a lè di olódodo. A kò lè ṣe ohun kan tí ó dára lójú Ọlọ́run fún ara wa - pàápàá pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ rere wa àti àwọn iṣẹ́ òdodo. Àsìkò tí a bá ti jọ̀wọ́ aiyé wa fún Kristi ni a jẹ́ olódodo ní ojú Rẹ̀.

Ojoojúmọ́ ni Ọlọ́run ń bínú sí àwọn ènìyàn búburú (Sáàmù 7:11). Àmọ́, Òun kì yóò dá wọn lẹ́bi mọ́ bí wọ́n bá kọ ọ̀nà búburú wọn sílẹ̀ (Ìsíkíẹ́lì 18:21-22). Yíyàn láti máa gbé ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ irú ìwà búburú kan (1 Kọ́ríńtì 6:9-10). Kíkọ ìgbésí aiyé yẹn sílẹ̀ bẹ̀rẹ̀ nígbà tí o bá kábàámọ̀ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì ṣe ìpinnu láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Ó ṣe pàtàkì púpọ̀ kí o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. O lè kábàámọ̀ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nítòótọ́, ṣùgbọ́n ìwọ kò ní agbára láti kọ wọ́n sílẹ̀ pátápátá kí o sì ní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, bí a kò bá tíì wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yìí nù nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì. Sátánì yóò múra láti sọ fún ẹ pé ìwọ kò yẹ lẹ́ni tó ń rí ìdáríjì Ọlọ́run gba mọ́, nígbà tí o bá ń bá a lọ láti máa gbé ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé òótọ́ ni pé inú Ọlọ́run kò dùn sí bí o ṣe ń gbé ìgbésí aiyé rẹ, tí yóò sì ṣẹ̀dájọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, Ó fẹ́ kí o yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yẹn, kí o sì gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún ọ nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀. Tí o bá ti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, Sátánì kò lè dá ọ lẹ́bi mọ́, nítorí a ti sọ ọ́ di olódodo. Ní àfikún, o kò ní gba ìdájọ́ láti wà nínú adágún iná, níbi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà títí láí (Mátíù 13:41-42). Lẹ́yìn náà, Jésù Krístì yóò di Alágbàwí rẹ lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Ó máa ń bẹ̀bẹ̀ fún àwọn tí wọ́n ti gbà á. O ní láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ tí o bá ti wọnú ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀, ṣùgbọ́n tí o bá ṣèèṣì dẹ́ṣẹ̀, ìwọ yóò rí ìdáríjì ní kété tí o bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì yí padà kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ náà, nítorí Ó ti san gbèse gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ (1 Jòhánù 2:1-2). Mọ̀ pẹ̀lú pé, Krístì kìí kọ ẹnikẹ́ni tí ó bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ láti ní ìgbàlà. Síwájú sí i, ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀, mọ́ (1 Jòhánù 1:7). Èyí tó túmọ̀ sí pé, kò sí ẹni tí ó wá sọ́dọ̀ Rẹ̀ tí yóò kọ̀ láti fún ní ìgbàlà, bí ó ti wù kí ẹ̀ṣẹ̀ náà rí (Jòhánù 6:37). Ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ yóò wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù pátápátá, nígbà tí o bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un - bí ó ti wù kí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ tóbi tó, tàbí bí wọ́n ṣe pọ̀ tó. Ìtura ńlá gbáà ni èyí jẹ́ fún ẹni tí a ti di ẹrù ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ wúwo lé lórí fún ìgbà pípẹ́!

Kò sí ẹni tí yóò wà nínú ọ̀run àpáàdì nítorí Ọlọ́run kò fẹ́ràn rẹ̀. Ó fẹ́ràn gbogbo wa, kò sì fẹ́ kí ẹnikẹ́ni nínú wa ṣègbé, bí kò ṣe láti wá sí ìrònúpìwàdà (2 Pétérù 3:9). Àmọ́, àwọn tí wọ́n kọ̀ láti ronúpìwàdà ẹ̀ṣẹ̀ wọn, tí wọ́n sì kọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ Rẹ̀ yóò gba ìdájọ́ láti dojúkọ àbájáde búburú, nítorí Ọlọ́run wa jẹ́ Onídàájọ́ Òdodo tí kò ní gbójú fo ẹ̀ṣẹ̀ rárá. Ní báyìí, tí o ti mọ̀ pé o lè yè bọ́ ìdájọ́ amúbíiná Ọlọ́run - ǹjẹ́ ìwọ yóò wá sí ọ̀dọ̀ Krístì bí? A kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni. Wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ nísinsìnyí. Ọ̀là lè pẹ́ jù!

Gbogbo ẹ̀dá lóní ìtẹ̀sí tí ó kún fún ẹ̀ṣẹ̀, tí a sì wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run nítorí àìgbọràn Ádámù àti Éfà (Róòmù 5:12). Ọlọ́run máa ń bínú sí ẹ̀ṣẹ̀, yóò sì ṣẹ̀dájọ́ ẹ̀ṣẹ̀. Nítorí èyí, Ó rán Ọmọ Rẹ̀ kanṣoṣo, Jésù Krístì sí wa gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti yè bọ́ ìdájọ́ ìkẹyìn Rẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀, tí yóò wá pẹ̀lú ìbínú àti òdodo (Jòhánù 3:16). Jésù Krístì san gbèse ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá lórí Àgbélébùú ti Kálfárì, kí a lè di olódodo. A kò lè ṣe ohun kan tí ó dára lójú Ọlọ́run fún ara wa - pàápàá pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ rere wa àti àwọn iṣẹ́ òdodo. Àsìkò tí a bá ti jọ̀wọ́ aiyé wa fún Kristi ni a jẹ́ olódodo ní ojú Rẹ̀.

Ojoojúmọ́ ni Ọlọ́run ń bínú sí àwọn ènìyàn búburú (Sáàmù 7:11). Àmọ́, Òun kì yóò dá wọn lẹ́bi mọ́ bí wọ́n bá kọ ọ̀nà búburú wọn sílẹ̀ (Ìsíkíẹ́lì 18:21-22). Yíyàn láti máa gbé ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ irú ìwà búburú kan (1 Kọ́ríńtì 6:9-10). Kíkọ ìgbésí aiyé yẹn sílẹ̀ bẹ̀rẹ̀ nígbà tí o bá kábàámọ̀ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì ṣe ìpinnu láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Ó ṣe pàtàkì púpọ̀ kí o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. O lè kábàámọ̀ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nítòótọ́, ṣùgbọ́n ìwọ kò ní agbára láti kọ wọ́n sílẹ̀ pátápátá kí o sì ní àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, bí a kò bá tíì wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yìí nù nípasẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì. Sátánì yóò múra láti sọ fún ẹ pé ìwọ kò yẹ lẹ́ni tó ń rí ìdáríjì Ọlọ́run gba mọ́, nígbà tí o bá ń bá a lọ láti máa gbé ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé òótọ́ ni pé inú Ọlọ́run kò dùn sí bí o ṣe ń gbé ìgbésí aiyé rẹ, tí yóò sì ṣẹ̀dájọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, Ó fẹ́ kí o yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ yẹn, kí o sì gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún ọ nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀. Tí o bá ti gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, Sátánì kò lè dá ọ lẹ́bi mọ́, nítorí a ti sọ ọ́ di olódodo. Ní àfikún, o kò ní gba ìdájọ́ láti wà nínú adágún iná, níbi tí ẹkún àti ìpayínkeke yóò wà títí láí (Mátíù 13:41-42). Lẹ́yìn náà, Jésù Krístì yóò di Alágbàwí rẹ lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Ó máa ń bẹ̀bẹ̀ fún àwọn tí wọ́n ti gbà á. O ní láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ tí o bá ti wọnú ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀, ṣùgbọ́n tí o bá ṣèèṣì dẹ́ṣẹ̀, ìwọ yóò rí ìdáríjì ní kété tí o bá jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì yí padà kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ náà, nítorí Ó ti san gbèse gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ (1 Jòhánù 2:1-2). Mọ̀ pẹ̀lú pé, Krístì kìí kọ ẹnikẹ́ni tí ó bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ láti ní ìgbàlà. Síwájú sí i, ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀, mọ́ (1 Jòhánù 1:7). Èyí tó túmọ̀ sí pé, kò sí ẹni tí ó wá sọ́dọ̀ Rẹ̀ tí yóò kọ̀ láti fún ní ìgbàlà, bí ó ti wù kí ẹ̀ṣẹ̀ náà rí (Jòhánù 6:37). Ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ yóò wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù pátápátá, nígbà tí o bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un - bí ó ti wù kí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ tóbi tó, tàbí bí wọ́n ṣe pọ̀ tó. Ìtura ńlá gbáà ni èyí jẹ́ fún ẹni tí a ti di ẹrù ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ wúwo lé lórí fún ìgbà pípẹ́!

Kò sí ẹni tí yóò wà nínú ọ̀run àpáàdì nítorí Ọlọ́run kò fẹ́ràn rẹ̀. Ó fẹ́ràn gbogbo wa, kò sì fẹ́ kí ẹnikẹ́ni nínú wa ṣègbé, bí kò ṣe láti wá sí ìrònúpìwàdà (2 Pétérù 3:9). Àmọ́, àwọn tí wọ́n kọ̀ láti ronúpìwàdà ẹ̀ṣẹ̀ wọn, tí wọ́n sì kọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ Rẹ̀ yóò gba ìdájọ́ láti dojúkọ àbájáde búburú, nítorí Ọlọ́run wa jẹ́ Onídàájọ́ Òdodo tí kò ní gbójú fo ẹ̀ṣẹ̀ rárá. Ní báyìí, tí o ti mọ̀ pé o lè yè bọ́ ìdájọ́ amúbíiná Ọlọ́run - ǹjẹ́ ìwọ yóò wá sí ọ̀dọ̀ Krístì bí? A kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni. Wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ nísinsìnyí. Ọ̀là lè pẹ́ jù!